# FIFI JESU HÀN ATI IWADII ẸJỌ́ RẸ̀ LỌNA ÈKÉ

## Matteu 26:47-68; 27:1, 2, 11-26

## ẸKỌ 63 – FUN AWỌN AGBA

**AKỌSORI: "A kẹgan rẹ̀ a si kọ̀ ọ lọdọ awọn enia, ẹni-ikãnu, ti o si mọ̀ ibanujẹ" (Isaiah 53:3).**

**A Mú Jesu bi Arufin**

Kristi ti ni iṣẹgun nipa ti ẹmi lori eekun Rẹ̀ ninu adura si Baba, irú adura ti o mu ki òogun Rẹ̀ dabi iro ẹjẹ. Ṣugbọn nisisiyii, O dide, Oun pẹlu awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ si fi pẹlẹ lọ pade ọta. O sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe afinihan ni sunmọ tosi; ki o si to pari ọrọ Rẹ̀, awọn ọmọ ogun ati awọn akọwe pẹlu awọn Farisi yọ pẹlu idà ati ọgọ. Judasi ni o ṣaaju wọn o si sare wa fẹnu ko Jesu lẹnu. A lero pe o yẹ ki oju ti i to bẹẹ ti ko fi ni fẹ ki awọn ọmọ-ẹyin iyoku ri oun, ṣugbọn eyi jẹ apa kan adehun ti o ti ṣe pẹlu awọn olori alufaa.

Jesu ti jẹ ẹni rere ati ẹni iwa pẹlẹ laaarin eniyan gbogbo. O ti n lọ kiri lati maa ṣe rere. Ṣugbọn nisisiyii awọn ọta Rẹ̀ dé loru lati mu Un lọ bi ẹni pe arufin ti o buru ju lọ ni Oun I ṣe. Jesu ko ba wọn jà; ṣugbọn iṣoro wa fun wọn lati mu Un. Nigba kan awọn olori alufaa ti ranṣẹ lati lọ mu Jesu, nigba ti wọn pada lai mu Un, awawi ti wọn ṣe ṣá ni pe "Kò si ẹniti o ti isọ̀rọ bi ọkunrin yi ri" (Johannu 7:46). Ọrọ ẹnu Rẹ lé awọn ọta Rẹ̀ pada sẹyin. Nisisiyii paapaa, ninu ọgbà, nigba ti ọpọ awọn eniyan buburu wá, wọn bì sẹyin, wọn si ṣubu lulẹ nigba ti Jesu sọ fun wọn pe Oun ni Ẹni ti wọn n wá. Oun pọ ju eniyan lasan lọ: Ọmọ Ọlọrun ni Oun I ṣe, O si ni gbogbo agbara ni Ọrun ati ni aye ti O le lò bi O ba fẹ ṣe bẹẹ. Ko ṣẹṣẹ ni jẹ ki awọn eniyan buburu wọnyii de Oun. Ọlọrun I ba ti rán legioni mejila sọkalẹ (eyi ti o jẹ́ ọkẹ mẹta aabọ -- 70,000) tabi ju bẹẹ lọ; ọ̀kan ninu wọn i ba si ti pa awọn ọta Kristi run lẹsẹkẹsẹ. Ṣugbọn eyi ki i ṣe ifẹ Ọlọrun. "Wakati Olugbala ti de" a si n fẹ pa A gẹgẹ bi Ọdọ-Agutan Irekọja.

**Ailera Eniyan Lai si Ọlọrun**

Fi awọn Angẹli ti Jesu ba pe sọkalẹ wé idà kekere ti Peteru lò. Gbogbo ohun ti Peteru le ṣe ni pe ki o gé eti ọmọ-ọdọ ni sọnu. Bi agbara eniyan ti ri ni yii bi a ba fi wé agbara Ọlọrun wa. Ṣugbọn bi o ba jẹ pe ifẹ Ọlọrun ni fun awọn ọmọ-ẹyin lati gbeja Oluwa wọn, ẹni kan ṣoṣo i ba ti ṣe ohun nla. "Bi Ọlọrun bá wà fun wa, tani yio kọ oju ija si wa?" (Romu 8:31); ati pẹlu "Ọkunrin kan ninu nyin yio lé ẹgbẹrun: nitoripe OLUWA Ọlọrun nyin, on li ẹniti njà fun nyin" (Joṣua 23:10). Ọpọlọpọ awọn ọmọ-ogun pẹlu idà ati ọgọ wọn, ki ba ti le ṣe nnkan kan bi o ba ṣe pe ifẹ Ọlọrun ni pe ki Kristi bọ́ lọwọ wọn.

Jesu jẹ ki awọn ọmọ-ogun mu Oun lọ si gbọngan idajọ; gbogbo awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ si fi I silẹ lọ. Jesu, Ẹni ti O fi ara Rẹ̀ ṣe ẹbọ ti o tobi ju lọ -- O fi aye Rẹ̀ fun awọn ọta Rẹ̀ -- o si dabi ẹni pe ko ni ọrẹ kan ṣoṣo ni wakati ti O wà ninu aini ti o tobi jùlọ yii. Njẹ a fẹran Olugbala fun gbese naa ti O ti san fun wa?

**Awọn Ẹlẹri Eke**

A kọkọ mu Jesu lọ si ile olori alufaa. A pe awọn ẹlẹri lati jẹri gbe E, ṣugbọn a kò ri ẹni kan, nitori Oun kò ṣe ibi kankan ri. Nikẹyin awọn ẹlẹri eke meji dide, ṣugbọn wọn ko fi ohun ṣọkan ninu eke ti wọn ṣe. Wọn ki ba ti ka ẹri wọn si, ṣugbọn inu bi awọn Ju to bẹẹ gẹẹ ti wọn fi gba pe o yẹ bẹẹ. Ọkan ninu awọn ẹlẹri naa wi pe Jesu ti sọ bayii pe, "Emi ó wó tẹmpili yi ti a fi ọwọ́ ṣe, niwọn ijọ mẹta emi o si kọ́ omiran ti a kò fi ọwọ́ ṣe" (Marku 14:58). Ṣugbọn eyi ki i ṣe ohun ti Jesu wi. Ọrọ Rẹ̀ ni wọnyii, "Ẹ wó tẹmpili yi palẹ̀, ni ijọ mẹta Emi o si gbé e ró" (Johannu 2:19). Oun n sọ nipa ara Oun tikara Rẹ̀ pe ẹni kan yoo wó o lulẹ ṣugbọn Oun tikara Rẹ̀ yoo gbe e dide. Oun kò sọ ohunkohun nipa ile.

Lẹyin naa, olori alufaa tun sọ fun Jesu ki o jẹri gbe ara Rẹ̀. Eyi naa pẹlu tun lodi si ofin Igbimọ awọn Ju. Bi eniyan tilẹ sọ pe oun jẹbi, a kò gbọdọ gba ẹri rẹ̀ ti o jẹ́ gbe ara rẹ̀. Nipa ẹri otitọ ti ẹni meji ti o dọgba ni a le fi da a lẹbi.

Awọn eniyan tutọ si Jesu loju; wọn kan An lẹṣẹ, wọn si fi I ṣe yẹyẹ. Gbogbo wọnyii ni o lodi si ofin awọn Ju. A kò gbọdọ fi iya jẹ arufin titi a o fi wadii ẹjọ rẹ pe o jẹbi; ṣugbọn ibinu ko jẹ ki awọn eniyan wọnyii ranti ofin wọn mọ́.

Inu bi alufaa si ijẹwọ Kristi to bẹẹ ti o fi fa aṣọ rẹ̀ ya, o si wi pe Jesu ni lati kú. Bi o tilẹ jẹ pe a ti pinnu eyi laaarin awọn Ju ki wọn to bẹrẹ ẹjọ. Idajọ yii jẹ́ aṣehan lati tẹ́ awọn eniyan lọrun ti wọn le beere eredi ti a fi pa A kiakia bẹẹ.

**Peteru Sẹ́ Ẹ**

Nibo ni Peteru wà nigba ti wọn n fi iya jẹ Olugbala bayii? O ti n tọ Ọ lẹyin lokeere lati ri ohun ti yoo ṣẹlẹ, o si fi ara rẹ̀ sinu ewu. Lọna kin-in-ni, o ti kuna lati ṣọna ati lati gbadura, nitori naa, ni o ṣe tẹ le Jesu lokeere. A ni lati ṣọra nipa iṣisẹ meji yii. Bi a ba ti fi adura silẹ ati kika Ọrọ Ọlọrun – biba Oluwa wa jiroro – aafo yoo ṣi silẹ pupọ laaarin awa ati Olugbala; bi a ba si pé ninu ipò bayii a oo sẹ́ Ẹni ti o ra ọkàn wa pada.

Nigba ti idanwo de si Peteru, oun kò ni agbara lati duro. Ọmọbinrin kan lasan ni o pe e ni ọmọ-ẹyin Jesu, oun si sẹ́. Eyi ni Peteru ti o ti leri pe oun yoo kú fun Jesu. Bawo ni a ṣe jẹ alailera to ninu ipá ti wa! Lai pẹ, awọn ẹlomiran mọ Peteru pẹlu, o si sẹ́ pe oun kò mọ Jesu rí rara. Nikẹyin inu bi i to bẹẹ ti o fi bura.

**Akukọ Kọ**

Lojiji akukọ kọ, boya igbe akukọ yii tilẹ dún ju àrá lọ ni eti Peteru. Ki ni ṣe ti eyi fi mu Peteru ta giri? Nitori Jesu ti kilọ fun un pe, ki akukọ to kọ, yoo sẹ́ Oun nigba mẹta. Jesu pẹlu gbọ iró akukọ yii Oun si yí oju Rẹ̀ pada si

ọmọ-ẹyin Rẹ̀ onitara ṣugbọn ti o jẹ alailera yii. A! wo bi inu Peteru ti bajẹ to! O mọ pe Oluwa jare gbogbo ẹsun ti O fi oun sùn yii; o jade lọ, o si sọkun kikoro.

Ṣugbọn ireti wà fun Peteru. O ronupiwada, ki i ṣe titobi ẹ̀ṣẹ awọn ẹlẹṣẹ ni kò ni jẹ ki wọn wọ ijọba ọrun, bi ko ṣe kikọ̀ ti wọn kọ̀ lati ronupiwada. Peteru ronupiwada a si yi i pada, nikẹyin o si wa di ọwọ̀n ninu ijọ, o si mu awọn ọmọ-ẹyin iyoku lọkan le. Ni ọjọ Pẹntekọsti, lẹyin ti oun ti ri Ẹmi Mimọ́ gbà o waasu iyanu kan to bẹẹ ti ẹgbẹẹdogun (3,000) eniyan fi ri igbala ni ọjọ kan. Lẹyin ọdun pupọ ti o fi ṣiṣẹ tọkantọkan o kú ikú ajẹriku nitori Kristi Ẹni ti oun ti sẹ́ nigba kan ri.

**A Ké Ẹjọ Naa Kuru**

Ni ile Kaiafa ni wọn ti ṣe iwadii ẹjọ naa nigba ti o si di owurọ, wọn fohun ṣọkan pe Jesu jẹbi ikú. Gẹgẹ bi ofin Ju, iru iwadii ẹjọ bawọnyii ni lati gbà to ọjọ mẹta: ọjọ kin-in-ni lati ṣe idajọ; ọjọ keji lati tun da a rò, iwọn iba diẹ si ni awọn onidajọ wọnyii gbọdọ ṣe mọ lati mu ọkàn wọn kuro ninu ẹjọ naa; ni ọjọ kẹta wọn yoo pejọ lati tun dibo. Bi onidajọ kan ba ti dibo ẹ̀bi fun arufin kan oun le yi ero rẹ̀ pada; ṣugbọn bi oun ba ti sọ pe "kò jẹbi" lakọkọ oun kò le yi ọrọ rẹ̀ pada mọ. Lọna bayii ni a n fun arufin ni anfaani gbogbo lati bọ́ lọwọ idalẹbi. Ṣugbọn a kò ṣe ẹjọ Jesu bayii, kanjukanju ni wọn fi ṣe e fun wakati diẹ ni iṣọ oru.

**Jesu Kò Lẹṣẹ**

Abẹ́ ijọba Romu ni awọn Ju wà, awọn ọran ẹjọ ti o ba si mu idajọ iku lọwọ gbọdọ lọ si iwaju awọn ara Romu fun iwadii. Nitori bẹẹ, ni owurọ kutu ni ọpọlọpọ eniyan ti inu n bi wọnyii mu Arufin wọn lọ si gbọngan idajọ Pilatu. Lẹyin ti Pilatu ti ba Jesu sọrọ fun igba diẹ o wi pe, "Emi kò ri ẹ̀ṣẹ lọwọ ọkunrin yi." Awọn Ju kò fẹ eyi. Wọn fẹ ki Pilatu ṣe idajọ ikú fun Un gẹgẹ bi ọrọ wọn lai wadii wò. Ko ha yẹ ki Pilatu gba ọrọ wọn gbọ́ bi?

**Kristi Niwaju Hẹrọdu**

Nigba ti Pilatu gbọ́ pe Jesu wá lati Galili o rán An lọ sọdọ Hẹrọdu, o rò pe nipa ṣiṣe bayii oun le ṣe alaidá ẹjọ naa. Hẹrọdu yii jẹ ẹni ti awọn ara Romu fi ṣe baalẹ agbegbe ilu naa. Inu Hẹrọdu dùn lati ri Jesu, nitori o ti n gbọ́ nipa iṣẹ iyanu Rẹ̀ gbogbo, o si ro pe oun le ri idán diẹ. Ṣugbọn Oluwa ki i ṣe iṣẹ iyanu Rẹ̀ nitori awọn ọlọfintoto. Nigba ti Jesu ko fesi si ẹsùn ti Hẹrọdu sùn Ún awọn ọmọ-ogun fi I ṣe ẹlẹya, wọn si fi aṣọ daradara wọ Ọ, wọn wolẹ bi ẹni pe wọn n bu ọla fun Un. Hẹrọdu ko fẹ ṣe idajọ kankan, nitori bẹẹ a mu Jesu pada sọdọ Pilatu.

**Jesu tabi Barabba**

Lakoko yii iyawo Pilatu ti lá ala buburu kan, ẹru si n ba a pe bi Pilatu ba lọ dá Jesu lẹbi iku, iyọnu nla yoo de ba wọn. Pilatu pẹlu n bẹru o si ranti pe aṣa awọn Ju ni lati dá arufin kan silẹ lọdọọdun nigba Ajọ Irekọja. Boya o mọ ọn mọ yan ẹni kan ti o buru julọ ti o mọ̀, apaniyan ti o ti n yọ awọn ilu lẹnu rekọja, o si jẹ ki awọn Ju yan ẹni ti wọn n fẹ laaarin janduku yii ati Jesu. O ro pe dajudaju wọn yoo yan Jesu, ṣugbọn wọn kigbe soke pe "Ki iṣe ọkunrin yi bikoṣe Barabba." Pilati ro pe, aanu yoo ṣe wọn bi oun ba na Jesu, nigba naa oun si le da a silẹ, ṣugbọn wọn tubọ kigbe si i pe, "kàn a mọ agbelebu" (o tun lodi si ofin wọn lati na eniyan ki a to da a lẹbi).

Pilatu mọ daju pe oloootọ eniyan ni Jesu I ṣe, ṣugbọn oun ko ni igboya lati mu iduro fun ohun ti o tọ́. O bẹru awọn eniyan, o duro niwaju wọn, o si wẹ ọwọ́ rẹ̀ lati ṣe awawi fun iwa ojo ti o hù, ṣugbọn a ko le wẹ ẹbi rẹ̀ nù niwaju Ọlọrun.

**Ijiya Awọn Ju**

Awọn Ju wi pe, "ki ẹjẹ rẹ̀ wà li ori wa ati li ori awọn ọmọ wa." I ba ṣe pe wọn mọ ohun ti wọn n sọ! Kò pẹ lẹyin ti Jesu kú, a pa Jerusalẹmu run, awọn Ju si jiya ti o buru ju lọ. Josẹfu opitan wi pe ọkẹ marundinlọgọta (1,000,000) ninu wọn ni a pa, a si kó ọkẹ marun-un o din ẹgbẹẹdogun (97,000) ni ẹrú. Ibẹrẹ ipọnju wọn ni eyi jẹ. Wọn n jiya sibẹ lonii nitori wọn kuna lati mọ Messia wọn nigba ti o dé, wọn si da A lẹbi iku ori agbelebu ti o buru ti o si kun fun itiju. Nigba ti Jesu ba tun pada wa, awọn Ju yoo mọ Ọn, wọn o si ṣọfọ Rẹ̀ "ẹniti wọn ti gún li ọ̀kọ" (Sekariah 12:10).

**AWỌN IBEERE**

1. Taa ni fi Jesu hàn? Eelo ni o ta A?
2. Nibo ni awọn janduku eniyan naa ti ri Jesu? Akoko wo ni o jẹ́ ni oju ọjọ?
3. Ki ni ṣẹlẹ si awọn ọmọ-lẹyin Jesu nigba ti a mu Un bi arufin?
4. Njẹ wọn wadii ẹjọ Jesu daradara?
5. Ki ni idajọ ati ẹ̀bi Rẹ̀?